# KUTA-KUTA PIN, ADELABU GBOLUDE KOHA TAN BI?




AWOGBA Omode fun Girl, Eyl, Hiku-ekin, Orere. Ra Tire Ni Ile Egbogi — ISE — Olodumare Okebola, Ibadan. 116, Great Bridge St., LAGOS

ELETI ỌFẸ
A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO

TO CLEAR
Gents Suede Court Shoe, Brown, Black & Grey
Before 50/- Now 42/6
Obtainable at :-
A. B. AKINYẸMI
10A Moloney Bridge St.
LAGOS.

VOL. VIII No. 458. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, MARCH 10, 1956. KỌBỌ MEJI (2d.)

## Kuta-Kuta Pin Adelabu Gbalude Ko Ha Tan Bi?

Lori iwadi iwa wuruwuru to f'arahan ninu Igbimọ Ibilẹ Ilu Ibadan ti Oluwadi Ọgbẹni Nicholson ṣe, ti alọ, alọ-ọrọ na da l'ori enia marun, Alaga Igbimọ ati awọn isọngbe rẹ mẹrin.

Lẹhinti Oluwadi pari iwadi rẹ wipe Ọgbẹni Adegoke Adelabu ti iṣe Alaga Igbimọ pẹlu awọn isọngbe rẹ mẹrin jẹbi owe-ibọlẹ nigbigba ati iwa ẹgbin miran, ni Alabojuto Ijọba Ibilẹ k'ọwe gba Igbimọ Ibadan ni imọran wipe ki nwọn pa ero pọ yọ awọn enia marun to fẹ ko iwa ẹgbin ba igbimọ kuro, ki ara igbimọ le mọ.

Ṣugbọn awọn Olugbimọ to mbẹ ninu igbimọ ibilẹ ilu Ibadan ṣe eti kunkun si imọran rere yi, gẹgebi bi a ti ṣe alaye ọrọ na si apakan iwe irohin wa yi, ti a ṣe akọle rẹ bayi:- IGBIMỌ IBADAN TUKA

Kini ẹti rope yio ri, nigbati Ọmọ ole ngun Ibaka? bi awọn enia ti iṣe Olugbimọ ti a yan sinu Ajọ Igbimọ ibilẹ ilu Ibadan ba tete f'epo Okoo j'aga, iba san diẹ, abọ eti kunkun re O. Emi ni Apanpa, emi ni Oluyọle, ko si bi nko tile ṣe nilu Ibadan, mo ṣebi a fi ọ ṣe ni, enia kan kii lagbara ju awọn to yan lọ.

Lori ọrọ iwadi yi Ile Igbimọ apapọ nla (House of Representative) ṣe gbọn Adelabu kuro ninu Minisita, to fi ọsan kan, oru kan ko ẹru rẹ jade ni agbala igbadun, ile Ikoyi, l'Eko. Nisisiyi ti Ijọba Iwọ-Orun tu Igbimọ ibilẹ Ibadan ka yi kut-kuta ko ha pin, Yọkọlu, ko ha tan bi?

VOMICURE




A Very Reliable Remedy for Vomiting During Pregnancy. Loss Of Apetite, Pains Below the Abdomen And All Other Ailments That Make Pregnancy Uncomfortable. No Prescription Needed. Just Buy A Bottle And Enjoy Good Health.
Obtainable from:-
EJIWUNMI
MED. STORE
LAGOS.
and Many other Medicine Stores

THE NATIONAL BANK

Of Nigeria Limited.

Ile ifi Owo pamọsi yi
Nfi ọna owo han ẹni
Bi o ba fẹ jẹ onisowo pataki ao
ran ọ lọwọ nipa wipe ao tọ ọ
si Ọna ti o dara, ao la eju rẹ
si Ọna owo lati ilu Okere wa
Bakanna si ni a tun nṣe iranlọwọ fun
gbogbo ọja ilẹ wa ti anta si agbaiye.

ILE IṢẸ WA NI EKO :—
37, Marina Street, P. O. Box 508, Lagos.

AWỌN AṢOJU WA NILU ỌBA NIYI :—
The National Provincial Bank (Overseas Branch)
1, Princess Street, London E. C. 2.
The Comptoir National Descompte, De Paris.
8/13, King Williams Street, London E. C. 4.

## Ilu Nla London Ki Oba K'abo

Aworan inu iwe wa yi nití Alaiyeluwa Ọba Elizabeth Keji, ti o ngbọwọ lọwọ Balẹ-ọkọ ilu, (Lord Mayor) ti olu ilu nla London, nigbati Balẹ na nki ọba ku abọ irin ajo rẹ silẹ Nigeria tiwa nibin,



Alaiyeluwa Ọba'binrin na pẹlu Ọ'ọlajulo ọkọ rẹ ni nwọn lọ sibi apejẹ nla fun ajọyọ ti abọde wọn lati Nigeria ti nwọn ṣe fun wọn ninu Gbọngan nla ti a npe ni Guild hall.

Nibẹ ni Alaiyẹluwa Ọba na gbe f'ẹsi si ọrọ iyẹsi ikini k'abọ ti Balẹ na, ti o si sọ ninu ọrọ rẹ wipe, oju on ki yio kuro lara awọn enia Nigeria ngbagbogbo ilera ati alafia itẹlọrun wọn ni adura atọkanwa on.

Kabiyesi o, Alaiyeluwa!

## Inunibini Se'ku Pani.

Nilu Pọta, nile awọn Ibo ni irohin ti kan wa wipe Ọkunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Akpan Etuk Obobo ara ilu ti a npe ni Ikot-Ukpong ni Kotu da l'ẹbi iku iyẹgi - mọlẹṣẹ pa lori ku Ọmọkunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Johnson Udo Ekpo Liba odo ti a npe ni Oblesn ni ọjọ kẹsan ọṣu May ti ọdun to kọja.

A gbọ wipe nigbati nwọn nro ẹjọ yi lọwọ nilu Opobo, Akpan sọ wipe on l'opa Johnson, nitoripe o ti pa ọmọ on ọkunrin lati nkan bi odun marun s'ẹhin.

Nigbati wọn bi lere wipe ki l'o ṣe ti oko file gbẹsan lati ọdun karun? Ọdaran na dahun wipe on ko ba Johnson pade nibi ipamọ ti ayo le gba on lati ṣe iṣẹ buburu na ni.

# Idahun Si Oro S. 0. T. Teledalase

L'ọna kinni, Ọgbẹni Tẹlẹdalaṣẹ ti fi idi irọ pipa rẹ han fun gbogbo agbaiye ri, ohun ti mo ṣe wi bẹ ni wipe Ọgbẹni Tẹlẹdalaṣẹ so sinu Iwe irohin Eleti-Ọfẹ ti ọjọ kokanlelogun oṣu January, 1956 wipe on ko rope ọmọ Maku kan wa ni Eko, gbolohun rẹ yi fihan mi wipe alai ko mọ pe ọmọ Maku wa ni Eko ni o je ki o purọ, nisisiyi ti o wa mọ yi ki o maṣe pa irọ mọ, nitori bi o ba pa irọ nipa ọrọ ilu Oke-Ọdẹ Ile-Ire emi yio ja ọ.

L'ọna keji o sọ wipe baba-nla iya rẹ ti oruko rẹ njẹ Agbera ni o kọkọ j'ọba ni Oke-Ọdẹ, irọ patapata ni eyi jẹ. Baba nla rẹ yi ti orukọ rẹ njẹ Agbera ko de Oke-Ọdẹ rara ki o to ku, ilu kan ti nwọn npe ni Ọra ni baba na ku si nigbati o nwaM aku bọ wa si Oke-Ọde bi ko ba da ẹ loju bi moti wi yi ki o lọ bere lọwọ awọn aṣiwaju rẹ ti wọn mọ itan Oke-Ọdẹ daradara.

L'ọna kẹta, o sọ wipe Baba nla iya on Agbera yi ni o bi Adeọba. Adeọba ni o bi Saliu, Saliu ni o bi iya on S. O. T. Tẹlẹdalaṣẹ O si tun sọ ninu iwe irohin Eleti-Ọfẹ na wipe baba iya on Saliu ni o tẹ Oke-Ọdẹ do, nigbati o sọ wipe Saliu to tẹ Oke-Ọdẹ do j'ọba, ọna wo ni baba nla iya rẹ Agbera tun wa gba j'ọba ni'lu ti ọmọ-ọmọ rẹ tẹ do? ẹnyin ọkawe, irọ funfun ti Tẹlẹdalaṣẹ npa niyi o.

Ọgbẹni Tẹlẹdalaṣẹ sọ wipe Oke-Ọdẹ Agodongbo, njẹ ẹnyin ọkawe gbọ Agodongbo pẹlu Oke-Ọdẹ ri ? eyi ara ! otitọ ni owe Yoruba to sọ wipe "Eni to ba fẹ jẹ ogun buruku, y'o pitan buruku" Tẹlẹdalaṣẹ tun fun ilu Oke-Ọdẹ ni orukọ tnatun lori irọ pipa. Odo kan (River) ni orukọ rẹ njẹ Agodongbo ni Oke-Ọdẹ, gẹgẹbi Eko ti wa pẹlu Ọsa, bẹni Agodongbo wa pẹlu Oke-Ọdẹ, njẹ a le pe ilu Eko ni Eko - Ọsa bi ? ko si Agodongbo ninu Oke-Ọdẹ, bi o ti ṣe njẹ Oke - Ọdẹ Ile-Ire ni a ti sọ sinu iwe ọsẹ tokọja.

Lẹhin bẹ, ṣe ẹnyin Ọkawe mọ pe ilu kan ni enia ti wa ki o to wa tẹ ilu miran do, a ko gbọ orukọ ilu ti baba nla iya Tẹlẹdalaṣẹ ti wa ki o tẹ Oke-Ọdẹ do, ako si mọ iru iṣẹ ti o nṣe. A si ti fi han pe iṣẹ Ọdẹ agbe'bọn ni Maku nṣe, iṣe rẹ ni a si fi npe ni Oke-Ọdẹ titi di oni Oloni yi.

Ki Ọgbẹni Tẹlẹdalaṣẹ lọ ṣiwọ niru apọn ti ko yọ o.

Emi ni tiyin
G. A. Maku

No. 49

## NOTICE

**Applications are invited for the post of Education Officer, Southern Cameroons. Particulars in Government Notice No. 379 in the Federation of Nigeria Official Gazette of 1st March. Applications to Secretary, Federal Public Service Commission, Private Bag No. 2586, Lagos. Closing date 14th April.**

No. 50

## NOTICE

**Applications are invited for the post of Assistant Meteorologist, British West African Meteorological Services. Particulars in Government Notice No. 378 in the Federation of Nigeria Official Gazette of 8th March. Applications to Secretary, Federal Pubiic Service Commission, Private Mail Bag, No. 2586, Lagos. Closing date 30th April.**

**Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe Ki O Si Polowo Oja Re Sinu Iwe Irohin Aladun Yi**


Let's have MUSIC! HEAR THE LATEST HIT NUMBERS

*Read this list of popular titles*

JZ 5879-Salami Adegbada/Itan Ogun Egba
,, 5880-Owokoniran/Al mi Okerayi) Yesufu Olatunji & His (Sakara) Band

JZ 5888-Jehovah Ran Ayo Siwa/Igbekole Enia-Baptist Church Choristers, Yaba

,, 5904-Oloja/Alafin) Seidu Sokoto &
,, 5905-Erinmi/Osise) His (Apala) Band

,, 5906-Alagbo/Irede -Rosey Show Mambo Orchestra

,, 5909-Durojaiye/Eda -Aminu Olaribigbe

,, 5910-Ijaw OTU/James Itti -Ijaw Youths' Orchestra



JZ5879-Salami Adegbada/Itan Ogun Egba
" 5880- Owokoniran/Alimi Okerayi) Yesufu Olatunji & His (Sakara) Band

JZ 5888- Jehovah Ran Siwa/Igbekole Enia-Baptist Church Choristers Yaba

,, 5904-Oloja/Alafin) Seidu Sokoto &
,, 5905- Erinm /Osise) His (Apala) Band

,, 5906- Alagbo/Irede -Rosey Show Mambo Orchestra

,, 5909- Durojaiye/Eda -Aminu Olaribigbe

,, 5910 -Ijaw OTU/James Itti - Ijaw Youths' Orchestra

*Sold by all the best stores*

HIS MASTER'S VOICE

"HIS MASTER'S VOICE" *yellow label* RECORDS

Distributed by THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED

## Abo Ejo Alufa Dedeke

Ile igbẹ'jọ ti awọn Ojiṣẹ Ọlọrun ti Olori Alufa, ẹni-ọwọ A W. Howells (Bishop of Lagos) yan lati ṣe ofintoto iwadi ọran ẹsun mọkanla nipa aiblkita, ilokulo ati iwa aiṣedede rẹ ti awọn fi sun.

Idajọ Olugbejọ na, Ọgbẹni Ayọdele Thomas ti iṣe adajọ atijọ ri pẹlu awọn isọngbe rẹ ni wipe Alufa Dedẹkẹ jẹbi gbogbo ẹsun na. Eyiti o jẹ pataki ninu awọn ẹsun na niti owo bi £15,000 ti Ijọba Iwọ-Ọrun fi fun ijọ C.M.S lati fi kọ ile ẹkọ mejilelogoji, ti o jẹ wipe nipa aiṣedede ile ẹkọ mẹrinla pere ni wọn kọ ti owo fẹrẹ tan.

Lori idajọ yi ni Olori Alufa ẹni-ẹwọ A.W. Howells fi idajọ rẹ le wipe ki a gba Iwe-aṣẹ (licence) ti Alufa T.O. Dedẹkẹ lati ọjọ kejidin'ọgbọn oṣu February 1956.

Kotẹmilọrun

Irohin ti a tun gbọ ni wipe Alufa Dedẹkẹ ti fun Lọya rẹ laṣẹ lati gbe ẹjọ na lọ si Kotu gbogbo-gbo (Supreme Court) wipe idajọ ti oluwadi ile igb'ẹjọ ti awọn ojiṣẹ Ọlọrun ṣe ko tẹ on lọrun.

Ẹjọ ti Lọya Alufa Dedẹkẹ Ọgbẹni G. B. A. Coker ati Ọgbẹni Adewale Thompson fi siwaju adajọ agba ọlọla Sir Joseph Henry Maxime de Cormond ni Kotu nla ni wipe ile igb'ẹjọ ti ojiṣẹ Ọlọrun ko lagbara lati ṣe ẹjọ ẹsun ti a fi Alufa Dedẹkẹ sun ati ikuna miran ti wọn sọ wipe o wa ninu ọrọ na.

Adajọ si da ẹjọ na duro lati fi asiko si riro rẹ.

### Baba Egbe Amerika Ba Ara Nigeria Soro

Eyiyi lo jẹ akọkọ ti Baba ẹgbẹ ilu Amerika yio ba enia dudu sọrọ. Ọgbẹni Muhammadu Liman, ti o lọ silu America fun ilọsiwaju ẹkọ lati Zaria College to lọ ba wọn ṣe awuye-wuye kan ni ilẹ Ijọba Amẹrika ti a npe ni White House, Washington.

A gbọ nigbati Baba ẹgbẹ na njade lọ ti o fi oju kẹrọ awọn enia dudu ilẹ Nigeria nwọnyi, o dara duro lati ba wọn mu faaji ọrọ sisọ diẹ Ẹni pataki ti osi ba sọrọ Muhamadu Liman. Iyi nla ni eyi si jẹ fun awọn Hausa

## Kereni Nla Lewu!

Alabojuto iṣẹ Ijoba (Federal Ministry of Works) sọ wipe awọn irin isalẹ Kereni nla (Carter Bridge) to gbe Kereni na duro ti ṣẹ ndi alarẹ, ti ko ni agbara mọ, nitori bẹ, gbogbo Mọto ti yio ba kọja lori Kereni na ko gbọdọ yara ju ibuso mẹdogun lọ fun wakati kan.

Kereni na nfẹ atunṣe gidigidi, ao si ṣe awọn atunṣe na nigbati awọn irin ti a ranṣẹ fun lati ilu Oyinbo ba de, ṣugbọn ki o ma si idilọwọ fun lilo Kereni na awọn ọjọgbọn onisẹ-ẹrọ ti sọ wipe ki a din irin Mọto ku lori rẹ titi ti ao fi tunṣe.

Ẹnyin Onimọto, awa Mọto ẹ tẹle ilana yi o.

Nitoripe ogun agbọtẹlẹ ki ipa arọ, Bi a ba mọ wipe iṣẹ nla ni Kereni yi nṣe fun wa, ki a ni iṣọra pẹlu lilo rẹ.


## Department of Information Services Western Region.

VACANCY FOR POST OF CINEMA OFFICER.

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment as Cinema Officer in the Department of Information Services, Ibadan.

Salary Scale - C(T) 2,3,4,5.

For full particulars see Western Region Notice No. 97 of the Western Region Nigeria Gazette No. 9 of 23rd February, 1956. Closing date 30th March 1956.



*to protect your cocoa from black pod disease and capsid*



FOUR OAKS spraying equipment *is the best!*



- *effective*
- *easy to operate*
- *safe*
- *increases yield*

FOUR OAK sprayers are available through your local Cooperative Supply Association Shop or Depot or through any Co-operative Produce Marketing Society or Union.

COOP WESTERN NIGERIA

# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS · CABLES & TELEGRAMS
28, Kosoko Street, Lagos "ELETI - OFE LAGOS"
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. VIII. NO. 458, LAGOS, SATURDAY MAR. 10, 1956.


## E Pa Idajo Iku Re! K'a Ma Ri......

Awọn Ogunna gbomgbo ilu Oyinbo Gẹsi, ninu ile Igbimọ wọn lẹnu lọwọlọwọ yi, ni nwọn da ni imọran wipe ki wọn ṣe l'ofin ki awọn Onidajọ Kotu maṣe da enia to ba pa enia ẹlẹgbẹ rẹ ni ẹbi iku mọ, wọn le ma fi iru awọn ọdaran apania bẹ s'ẹwọn gbere e fun ọjọ aiye won

ỌGBỌN AGBỌNJU, WAHALA L'O NFA WA.

Nigbati ari amọran yi ka ninu awọn iwe irohin, ọrọ ti o jade l'ẹnu wa ni orin ti awọn Yoruba aiye igbani ma nkọ bayi wipe:-

"K'a mari. ija Ibadan k'a mari l'odun".

Irufẹ ofin agadamaṣa bayi ki Ọlọrun majẹ k'ari nilẹ tiwa Nigeria yi, nitoripe ko si ohun to fa iru imọran bawọnyi wa ju ọgbọn-agbọnju ti Ehoro fi fi ẹpọn rẹ leke oko lọ, fun awọn Oyinbo Gẹsi.

IWỌ KO GBỌDỌ PANIA

Bẹni Oluwa wi ninu Iwe mimọ Bibeli ti awọn Oyinbo Gẹsi fiṣe amọna wọ'l'u wa, ti nwọn si fi kọ wa gẹgẹbi ofin Ọlọrun alaye, ki a ma ṣeṣẹ sọ ti Alkoran mimọ mọ tabi ki a tilẹ ko ti ọrọ Ọlọrun to kọni wipe "Iwọ ko gbọdọ pania" ti si apakan na, awọn Yoruba papa ti fihan wa mọ daju wipe, "Ọmọ ki ipa ọmọ jaiye".

Nilẹ Nigeria tiwa nihin, awa ko ro wipe irufẹ ofin bẹ leṣe iṣẹ rere kan fun wa nitoripe bi a ti nṣe idajọ iku oro iyẹgi-mọlẹṣẹ pa fun awọn oninu buruku enia ti o ba pa enia to yi, ako ṣai ngbọ kakiri, irohin wipe wọn pa ẹnikan nihin, nwọn pa ẹnikan lọhun yika ilẹ wa nihin, ki a tun wa ṣe ofin ki a ma tun pa apania mọ, ẹnmọ de myẹn.

KOSI IDARIJI FUN APANIA

Bẹni awọn Alufa Musulumi fi kọ wa ninu Alkoran mimọ, nitorina, ẹṣẹ ipania jẹ ohun pataki ti Ọlọrun Olodumare kọ fun awa ẹda enia ọwọ Rẹ patapata. Bi iru ofin maṣ'anfani sondoko bayi ba yọju s'ode nilẹ wa, gbogbo awọn enia oninufufu ti o jẹ pe idajọ ipa ni oro ti a nṣe fun ẹniti o ba pania mba lẹru ti ko jẹ ki wọn le ṣe iṣẹ buburu wọn, ni nwọn yio ni ifọkanbalẹ wipe, ṣe ẹwọn ni wọn ma ju awọn si; bi o ba si pẹ awọn le ṣo-rire, ki nwọn da awọn silẹ—ko tun si ibẹru mọ.

Adura ti ni ki Ọlọrun majẹ ki iru ofin bayi de ilẹ wa, Ọmọ ki ipa ọmọ jaiye.

## OLOJO IBI. ODUN METADINLADOTA

A ba Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ Ọlọla Alakoso Ijọba Iwọ - Orun yọ fun ti ọjọ ibi rẹ to ṣe ni ọjọ kẹfa oṣu March yi.

Ape sindodo ni apejẹ ọsan ọjọ na, ti awọn Ọlọla ati Oloye, awọn ẹnibi Oba Ọni ti Ile - Ifẹ, ati Ọgbẹni R. A. Doherty ati agunlẹyinju iyawo rẹ pẹlu awọn Minisita pẹju peṣẹ sibẹ

Ki Ọlọrun fi ọpọlọpọ ọdun han wa o.

## Kil'o Fa Irokeke Ogun?

Ninu ọsẹ to lọ niwaju lọhun nigbati Gẹsi Amẹrika, France, Roṣia, Jamani, Italy, Japan, China, Belgium, Austria ati ọpọlọpọ awọn ilu miran nṣe atunṣe wipe ki ogun miran maṣe tun bẹ silẹ nitoripe omi eyiti a ti ja kọja lọ nigba meji koiti gbẹ lori wa, A gbọ wipe bi nwọn ti nsọrọ na nṣe ni awọn Roṣia nyi bọrọ ṣa. Roṣia fi ọrọ na le ogun, Amẹrika fi le ọgbọn Gẹsi tatọ soke, wọn fi foju gba a.

Ọrọ yi ko jẹ didun inu awọn Oyinbo Roṣia, inu bi wọn tobẹ ti wọn fi fa agbọn imu ja lọsẹ to lọ niwaju lọhun, o taku wipe on ko ni tilẹ ni ba ẹnikankan ṣe ipari ija mọ. Bi ogun ba le de ki o de Roṣia ko bẹru Atọmiki Bombu nitori nwọn ni baba nla rẹ lọwọ, bi ogun na ba si de, Roṣia yio jagun na de gongo.

Ọpọlọpọ awọn enia ti o gbọ iru ọrọ yi nino ẹrọ Radio ti bẹrẹ si fidi fọgba fidi fọ awo nitoripe ẹniti ṣango batoju rẹ wọle lailai oluwarẹ ko ni bu Ọbakoso, Ẹniti ogun 1914 ati ti 1939 ṣ'oju rẹ, ko jẹ gbadura pe ki ogun kode

Ṣe ẹ kuku mọ wipe awọn Gẹsi ko fẹran ihalẹ. Nigbana ni Ọgbẹni Sir Anthony Eden dahun wipe. "Aguntan mọran ṣe sọgun, ọgbọn inu rẹ pe ẹgbeje." Ki awọn Roṣia maṣe tun ṣe ihalẹ ogun mọ, ko si ẹniti ko nitirẹ lọwọ, ṣugbọn bi ogun ba di ogun wipe a nlo Atomiki Bọmbu fun ara ẹni, o da on loju to ọsẹ awujẹ wipe, ilu Stalingrad, ati Moscow ko ni si lori ilẹ aiye, boya eyi ni yio ṣe opin ilẹ Yuropu (Europe).

Nigbayi ni Ọgbẹni Mockton ti o nṣe olotu ogun jija nilẹ Gẹsi fi ọwọ gba ori pẹpẹ, o dahun wipe, bi o ba jẹ wipe ogun di ogun Atomiki Bombu ao fi awọn ọkọ oju omi, ti ofurufu ati ọkọ ogun ko gbogbo awọn Ẹgbẹta ọkẹ enia ti o mbẹ ni England lọ silu miran, ki awọn to tọwọ bọ iṣẹ. Boya ogun na ni yio jẹ opin si ilẹ Oyinbo nitoripe ko ni ku ile kan lori ile mọ, nitori Atomiki Bọmbu ko ni fi wọn lọrun silẹ.

## Owo Koko Di Adojo Poun

Ni ọjọ Satide tokọja ni Alabojuto inawo Ijọba Iwọ orun, (Minister of Finance) Ọgbẹni F.O. Awoṣika ṣe alaye lori owo tita Koko to din s'ẹhin di adọjọ poun £150 ṣugbọn fihan wipe gẹgẹbi ileri ti Ijọba Iwọ-orun ṣe fun awọn agbẹ Ijọba yio ma san igba poun (£200) fun awọn Agbẹ fun Tọwun kan Lai ko ni jẹki awọn iyatọ ẹdin'wo to lori Koko.

Ọgbẹni Awoṣika tun tẹ siwaju lati fihan wipe pẹlu owo girimọyan ti Ijọba yio lo fun ọdun 1956/57 itẹlọrun mbẹ, nitoripe owo apo ijọba yio ṣeku silẹ daradara ati wipe gbogbo iṣẹ pataki pataki ni Ijọba nṣe leto-leto ti o si nyọri si dede, Gbogbo ile Igbimọ ati ijọ ti Ijọba pẹlu ijọ ti Alatako ni o da muso fun u.

Koko d'nwo, Koko 'o dinwo, Ijọba Iwọ-orun yio san owo pe perepere fun awọn agbẹ.


## LAGOS RACE CLUB

### POSTPONED CHRISTMAS MEETING

The Postponed Christmas Meeting will be held on Saturday 17th March and Saturday 24th March, 1956. Owners who have entered horses for the first two days of the Meeting are required now to pay for their entries.

Entries not paid for by 10th March, 1956 will be scratched.

EASTER MEETING

Saturday 31st March, Monday 2nd APril, Saturday 7th and 14th April, 1956.

## Gehin-gehin

Dan egbogi yi wo fun ẹhin ti o ba di wipe ẹhin ndun enia de ipo ti ko le bẹrẹ, Kindinrin lo fa a Nitoripe iṣẹ Kindinrin ni lati sọ idọti kuro ninu ẹjẹ ara enia, nigbamiran ewẹ ko ni ṣiṣẹ deedee. Ẹhin ti o dun ni jẹ ikilọ fun enia wipe Kidinrin rẹ ko ṣiṣẹ to, o si nfẹ iranlọwọ egbogi De Witts ni a le ro pe o le ṣe iwosan na Nitoripe egbogi na ko ṣe iru iṣẹ bẹ ti ri. Dan wo, lọ ra ọkan ni ṣọbu.



Ohun to da wa loju niwipe Egbogi DE WITT'S jẹ eyiti a ṣe tenitoni ohun elo rẹ agbegbo lo si mọ.

**DE WITT'S PILLS**
for Kidney and Bladder Troubles



## Kere o!

A ti ni oriṣiriṣi ogun Germany to ṣẹṣẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**
MEDICINE STORES
7, Egerton Road, Lagos



## Now Available

BUGLES, BEDSTEADS
PAINTS, DISTEMPERS,
SAFES Etc.
Just Write, Call Or Phone 21372

**IKORODU TRADING COMPANY**
20/28 BALOGUN STREET
(P. O. BOX 395) LAGOS.
AND
NEW COURT ROAD,
IBADAN



*Awọn Ẹbi Ogbe Alayọ sọ wipe*

# OVALTINE

wa fun ilera ati inudidun!









AWỌN ẸBI OGBE

ti awọn gba ẹbun ti apapọ Ẹgbẹ kede sinu "Sunday Times" fun idije awọn ẹniu ẹbi rẹ ba ni inudidun ju ṣe awọn eto inudidun kan ti ko mu inira dani. Jẹ onjẹ atata, sun fọnfọn, ki o ma si ṣe wahala! Bẹni awọn Ẹbi Ogbe nmu OVALTINE lẹmeji lojumọ, larọ at lalẹ. OVALTINE nfi gbogbo awọn ohun ti o le fun ni ni alafia ati ilera kun onjẹ ti o ba njẹ, o nfun ara ni okun ati idẹra ati igbadun orun. Wa si ji dide pẹlu isọdọtun agbara ati alafia. Ṣe afarawe awọn ẹbi Ogbe, ma a mu OVALTINE nitori ilera ati inudidun.




# OVALTINE

*-ko si ohun ti o dara to!*

OWA 1607



## FOR RENT

Chairs, Flags and Bunting
APPLY :- S. A. Majẹnrahun (Alias Ọfẹ)
3, AIBU STREET, LAGOS.

## IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

**Enyin abiyamo e wa ra OMORELA o dara pupo fun awon omode.**

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

OMORELA BABY MIXTURE
(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN IGO KAN)

O wa lọdọ :—

COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemist)
10, VICTORIA STREET, LAGOS

## AWON OJOGBON ONISE-GUN EHIN FI YE WA WIPE

BI A BA NFI EGBOGI







COLGATE DEN-TAL CREAM FO EHIN

KO NI JEKI EHIN ENI BAJE, O DA-RA PUPO



Işẹ ti Egbogi yi nşe ni wipe, eyiti o nho bi ọṣẹ yẹn, yio wọ gbogbo pala-pala ehin, yio si yọ gbogbo ajẹsi kuro, ko ni jẹki ẹnu run, ko si ni jẹki ehin bajẹ.




O njẹki ehin funfun, enu ko si ni run mọ.


## An African Studies In London

My Impressions Of University Life

By

Bayo Bamgbose

To go to Britain, to see that ancient and powerful country, to meet British people and to study there was an experience I had longed to have; and when the opportunity came, I seized it happily. And so I left my home in Nigeria, West Africa, to study economics and to meet English people in their homes

Before I entered London University in 1952, I had already lived in London for about two years, working and doing the necessary pre - University studies. During my first 15 months in England, I live with an English Christian couple, who took me in as a member of the family. They were very nice people and I still keep in touch with them.



Students at the London School of economics and Political Science University of London, relax after lunch are (left to right) T. A. Otubanjọ (Nigeria), Franz J. Meder (Western Germany), M. Blunt (Britain), I. F. Aiyelagbe (Nigeria) Miss J. Yesu Das (Trinidad) and Z. O. Dibiaezue (Nigeria).

FRIENDLY PEOPLE

In October 1952, I became a student in the University; I was enrolled in the Faculty of Economics at the London School of Economics and Political Science.

From the very first day I sensed a different atmosphere. The impression was that of a noisy, happy, friendly group of young men and women of different races rushing from one room to another in search of knowledge.

Like most African students, I was very much older than the average 'English student. But, like them again, I did not really look my age. Why? Because we wear well in Africa, I was told.

In my first year, I became acquainted with an English student who was ten years my junior. But we got on so well together that I forgot my age, at least, for the rest of my undergraduate days. What is more, I made friends with other students in the College.

At the end of the second year, we had the results of our Part I examination and life became more settled and more interesting. The third year was about the most eventful. With Part I examination behind, we seemed to think that the worst had been gone through. That had been the most difficult part of the course. Now then, time for a little relaxation. It was also the time to get to know better those who had survived the

(continued on page 7)

## An African Studies In London

(Continued from page 6)
ordeal of the second year and we made the most of it.

A WARM RECEPTION

We had several outings with some of the College societies, among which were visits to Oxford and Cambridge Universities. More thrilling to me, perhaps, were the visits I made to the homes of two English student friends of mine. Their families gave me a very warm reception, and the memory of those meetigs will always be a happy one.

Most colonial students seemed to be more concerned with their studies than with the social aspect of University life. I was no exception. Nevertheless, I was a committee member of the London Inter-Faculty Christian Union and the Liberal Society of the College. In these societies and in the weekly Students' Union meetings, there was a lot of interest and amusement. Most fascinating and, at the same time educative, was the enormous variety of opinions, freely expressed, on questions which ranged from "Reincarnation" to "Commonwealth Students in Britain".

Not only this: one got to know more about other countries and people than one could from Books. This free interchange of ideas among students from all parts of the world is an essential part of University eduction, I think. It certainly can promote international understanding.

I should record that I noticed no discrimination against colour or race from my fellow students: not even at students' gatherings outside my own College. Student was a student whether he came from Somerset in England, from Delhi in India or from Kingston in Jamaica. If you were ready to mix and carry about with you your humour, your wit and of course, your smiles, a happy time awaited you

OPPORTUNITIES

I would admit readily that life may not be the same for all students. After all, the London School of Economics is only one of several college. in the University. You may even think I have been lucky in some ways

It must be said however, that a lot depends on the type of person one is and the sort of life one wishes to live in England.

dificulties in living away from one's own country, and I did have my full share of these. But if one wishes to mix and have a happy time, there are opportunities if one cares to look for them.

Even out-side university, there are many organisations like the Victoria League and the British Council, which are ready to help. Quite honesty, I would not have liked to miss the opportunity of living and studying in England.

## Awon Omo Orisa

A ti ngbọ lẹnu awọn Aborisa wipe nigbati ọmọde kan ba bẹrẹ si sọkun nigba gbogbo, nwọn a sọ pe boya ọmọ na nfẹ ya ọmọ orisa. Dada ni. Nwọn sọ wipe bi nwọn ba nkọrin bayi fun u ọmọ na yio dakẹ.

Dada ma sọkun mọ
Ero Ajasẹ mbọ lọna,
Fun mi lowo kan atamori
Inu ọja la nlọ, ero ọja paramọ
Dada ko lasọ enia ti bora,
Olukugi, konkọsọ Kugilala, Olukugi, kọnkọsọ Kugi lala,
Dada Dada ko ni ku,
Dada ko ni run
Dada ko ni fi Anobi silẹ k'olọ bọrisa
O dade owo o, Bandele
Era, ẹra, ẹra, Bandele.

Bayi ni ohun na ti a ma ngbọ l'ẹnu awọn Baba Olorisa aiye igbani Orin ti o gbẹhin yi tiha n wa wipe awọn Aborisa papa mọ pe Ọlọrun Ọba mbẹ, nigbati nwọn nkọrin na bayi:-

Dada ko ni fi anobi silẹ k'o lọ bọrisa

## Igbimo Ibadan Tu Ka

Ni ọjọ Monday ti iṣe ọjọ karun oṣu February yi ni Alabojuto Ijọba Ibilẹ ti Iwọ-orun fi iwe ranse si Akọwe Igbimọ Ibilẹ Ibadan ọrọ inu iwe na lọ bayi:-

Nigbati a ro siwaju Alabojuto ro si ẹrọ lati ṣe atunṣe ofin ti yio tu igbimọ na ka.

Nitorina mo fi oyi sọ fun yin wipe Ijọba Iwọ-orun ti paṣẹ ki a tu Igbimọ ibilẹ ka leti ofin apa kẹwa (2) ti ofin Ijọba ibilẹ ki a si yan Igbimọ titun. Mo fi ẹ da ofin titun ti Ijọba Iwọ-orun gba sinu wẹ yi.



OLOYE ROTIMI WILLIAMS

Alabojuto Ijọba Ibilẹ sọ wipe ki ntọka igbimọ ṣi iwe mi No. 28502/33 ti ọjọ kẹrindilogun oṣu January 1956. Lẹhin igbimọ ti ẹ ti yan lati ṣe aṣaro lori iwe mi na, ko si ohun kan ti ẹ ṣe lati tẹle imọran inu iwe na, eyi l'omu ki alabojuto pinnu wipe Igbimọ ko fẹ ṣe amuṣẹ lori ilana ti oluwadi Ọgbẹni Nicholson ṣe tabi ki Igbimọ wẹ ara rẹ mọ kuro ninu iwa ibajẹ ti ti oluwadi Ọgbẹni Nicholson da Alaga ati awọn olugbimọ mẹrin lẹbi rẹ, iyẹn nipe Igbimọ f'ara mọ iwa wọn na.



Mr A DEGOGE ADELABU

ETO OFIN TITUN

Awọn alabojuto ti ao yan si Igbimọ yio ni agbara gẹgẹbi ti Igbimọ ti a tuka, Alaiyeluwa Olubadan ni yio si jẹ Baba ẹgbẹ wọn (President) awọn enia ti ao yan ko gbọdọ ju ọgbọn enia lọ. Alabojuto Ijọba ibilẹ ni yio si yan awọn enia na, nipa bẹ iṣẹ igbimọ y o ma lọ dede.

GBERE RE ZIK !

A gbọ wipe Ọlọla Dokita Azikiwe ti iṣe Alakoso Ijọba Ila-Orun (East) f'aramọ idajọ Ijọba Iwọ-Orun nitoripe ako le fi awọn enia rudurudu ṣe Ipilẹ Ijọba, ominira wa ti a nlepa ṣe lọwọlọwọ yi. Akonijẹ ẹgbẹ Alakuko kọ ọrọ iwọsi.

## Kilo Mu Oyun Ba Okunrin?

Ipo tabi aye ti iijoba fi awọn Commissioner wọn si ni wipe awọn pẹlu Gomina lo mbẹ nipo kenna.

Irohin ti a gbọ l'ọsẹ yi ni wipe Ọgbẹni kan ti ijọba ilẹ yi fi ṣe Commissioner silu Ọba lati ma ṣe aṣoju fun wa ni a gbọ wipe, o nlọ kọ iṣẹ Loya. Ki lo ba ọkunrin ba oyun kẹ? ọrọ na koiti ye wa si, o si nṣe wa loju su.

LAGOS RACE CLUB
NOTICE TO OWNERS.

**All jockey's licences issued by the above Club expired on 30th November, 1955 and can now be renewed at the cost of £2 each.**

## Orunmila Gbori Lowo Awo Ife

Lati Owo Eso Ikoyi

Agiri-wo-malaja, Awo Ifẹ lo difa fun gbogbo awo Ile Ifẹ Ọyẹlagbo A bu fun Ọrunmila, a ni ki nwọn o ru nwọn ni awọn ko ni rubọ Alaikọfa Awo Ọrunmila ni jusilẹ, mo ni jusilẹ O ni alaikofa awo lọ ṣe Alara to fi de'le Ara alaikofa awo lọ ṣe Ajero to fi dero Ijero, Aigbọfa lo ṣe Ọrangun to fi de'le Ila, etc., Itan na lọ bayi wipe Agirimọlaja jẹ ọmọ awo fun Ọsanyin on lo kifa rẹ fun awọn awo mẹrẹdogun ti o mbẹ ni Ifẹ. Ṣugbọn kaka ki nwọn gbọ ki nwọn ru, nṣe ni nwọn bẹrẹ si fi ṣe yẹyẹ wipe, ẹniti a ko ba mu wọ Igbodu, ki a si tẹ nifa, ntun tẹ enia logbe.

Ṣugbọn Ọrunmila gbọ nipa ọrọ yi, o yara rubọ, o si ṣe etutu, ko pe ti Ọrunmila rubọ agbebọ adiẹ kan tan, ni Onişẹ de wipe Ọlọfin npe gbogbo awọn Awo Ifẹ. Ọrunmila ko fẹ ki awọn awo mọ pe on wa, o gba ọna ẹhinkule Ọlọfin. Bi o ti nlọ lori obinrin arugbo kan ti o joko lẹba ọna, bi o ti ri Ọrunmila, o ni ki o fun on ni onjẹ nitori ebi npa on.

Orumila fun ni ẹkọ meji ati itan adiẹ ti o fi şetutu obinrin na jẹ o yo tan, o bere ibiti Ọrumila nlo? Ọrumila dahun pe Ọlọfin lo npe wa, Iya na şe ofofo fun u wipe Ọlọfin nfẹ din wọn wo ni, Wundia kini ti o jẹ ẹnia dudu, Ọmọnidun loruko rẹ niẹ. Eyi ekeji ti o jẹ pupa lo njẹ Ọmọnidẹ. Nigbati Ọrumila gbọ bayi tan, o wọ, afin Ọlọfin lọ, o si ba ti ẹsẹ awọn Awo Ifẹ ti pe şanşan.

Ọlọfin wi fun awọn awo wipe, on ni ọmọbinrin Wundia meji, ekini nfẹ fẹ ogboju Awo lọkọ, ekeji ẹwẹ nfẹ ni ogboju awo lọkọ Awọn ọmọbinrin mejeji na ni wọnyi; ẹnikẹni ti o ba le kifa mọ orukọ wọn ni yio ṣọkọ wọn.

Gbogbo awọn Awo nwọnyi lo kubo patapata. Nigbati o kan Ọrumila, o jan iporun rẹ mọlẹ, o r i ejogbe, o kifa lọ şa, şa şa, o wipe eleyi dudu yi, njẹ ọmọnidun, eyi pupa njẹ Ọmọnidẹ. Ariwo ta kuhu, Ọlọfin paşẹ pe ki a gbe Ọrumila, ki nwọn wẹ fun ki a fun n i aşọ to dara. Ọrumila mura tan o mẹkun sẹkun igbe o mohun şohun iyẹrẹ, o njo o nkọrin bayi wipe, Ọmọnidun, Ọmọnidẹ ba mi gbe yawo o jare, Ọmọnidun, Ọmọnidẹ. Lati ọjọ na ni Ọrunmila ti sọ wipe, on ko nşe ifa Olobinrin kanşoşo.

## Akintola Pegede

Ọrọ pataki ti nwọn ti nfa lati nkan bi ọdun mẹrin s'ẹhin ninu Ile Igbimọ Iwọ-orun ni ọlọla oloye S.L. Akintọla yan'ri rẹ ninu Ile Igbimọ apapọ ala ti Nigeria nilu Eko ni ọjọ Tuesday ọsẹ yi.



OLOYE S. L. AKINTỌLA

Oloye Akintọla ti işe Akonijẹ ijọ Alatako ninu Igbimọ nla (House of Representative) mu wa siwaju Igbimọ wipe kia bẹ ijọ awọn Minisita ki wọn şe atunşe ofin aigbọdọ şe ọti ni ilẹ wa Nigeria ki a le ma şe ọti laisi ibẹru ofin amunimuye nilẹ wa nihin.

Oloye Akintọla sọ wipe on ni i f ọ k a n b a l ẹ wipe ile Igbimọ yio gba imọran na nitoripe bi a ba g b a k i a maa şe ọ t i nilẹ wa nihin, ale şe ofin ti yio dabobo awọn enia le lori.

Ọgbẹni V. D. Phillips gbe lẹsẹ o si sọ wipe ijọba Iwọ-orun ti gba irufẹ ofin yi, ati pe yio şe iranlọwọ sinu owo apo owo apo Ijọba nipa owo iwe aşẹ gbigba fun awọn to ba nşe Ọti ati owo ti Ijọba yio mari l'ori Ọti ti wọn ba şe fun tita.

Ọgbẹni Ayọ Roşiji ati Ọgbẹni M. A. Ọlanrewaju gbe lẹsẹ, agbare-gbabọ ile gba a.

Ẹnyin ọkawe, ẹ ş'akiyesi Işẹ ribiribi ti awọn olotu ẹgbẹ afẹnifẹre (A.G.) nşe fun ire ilu wa. Ọkan pataki ni eyi jẹ.

Oloye Akintola pegede o fi gbọrọ jẹka o pegedede.


## AWO REKODU ATATA

Wa ra awọn awo rẹkọdu atata, ti o gbadun, to dun leti, ti o da ni lara ya, ti o si jẹ tuntun (ti asiko). Ọpọku ọyọku si ni owo wọn.

WA1739 Mojẹlewa; Ebi labẹ agbada - Lagbondoko (elerin).
WA1740 Işọkan Nigeria; Eko a toro " "
WA1750 Aiye ko fẹ talaka; Agbẹ aroko - Ajengbe (Apala)
WA1751 Adelabu Pẹnkẹlẹmẹsi Ogunmọdẹde " "
WA1752 Orin Aje; Ẹ ba wa yọ " "
WA1768 S. Aka; Lasisi Alao - S. Aka (sakara)
WA1769 Sisi ati alapata; Iya Ẹgbọ Ashakẹ " "
WA1770 Owolagba; Ọba to l'aiye " "
WA1777 A ju ra wa lọ; Nibi ka lulu - Aruna Ishola (Apala)
WA1803 Olu Ẹpẹ; Alafin; Ọba Alako - Dambawa (Apala)
WA1804 Dele Wulin; Suwebatu Ayinke " "
WA1805 Orimolusi; Njemanze; S.L. Edu

6/- fun awo kan. Owo-ọkọ jẹ 2/6d fun awo mẹta; 3/6d, fun awo mẹrin si mẹwa ilọpo meji ni owo-ọkọ Oke-Okun.

### The Egba Trading Aradan Stores

18, Denton Bridge St.,
P. O. Box 2, Ebute-Metta

## Western Region Production Development Board.

DISTRICT INSPECTOR OF WORKS (WATER).

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment as District Inspector of Works (Water).

Candidates should be conversant with the laying and Servicing of Everite and Iron Mains, installation and servicing of both Centrifugal and Piston Type Pumps and Diesel Engines and be able to undertake complete overhaul of such equipment. At least ten years previous experience is necessary.

Salary will be in the range of £660; £700 x 42 - £863; £902 x 42 - £1,070 (plus expatriation pay where applicable), point of entry depending on qualification and experience.

Applications, in the applicants own handwriting, giving full details of qualifications and experience, should be forwarded to reach

The Personnel Secretary,
Western Region Production Development Board, Ibadan

not later than the 24th of March, 1956.

Only applications of those selected for interview will be acknowledged.

## AKIYESI PATAKI

### Bi o ba fe ra Eleti-Ofe tabi o fe polowo oja sinu re,

LQ SI:-

### 18, Race Course Road,

OKE—PADI, IBADAN.

E mu irohin wa tabi ohun to ba je edun okan yin, ki e si ma ka Iwe ELETI—OFE nigba gbogbo.


Printed & Published by The Union printing and Publishing Company, 28 Koecko Street P.O. Box 467 Lagos Phone 23276